Chief Secretary to the Government

IROHIN ẸJỌ *LAGOS DAILY NEWS* MBẸ NIHIN NI YORUBA TI O JINA.

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO. 285 SATURDAY, JULY 28, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

NIGERIAN SECRETARIAT
1 AUG 1928
LAGOS

**White's Radical Gonkiller.**

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoca.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.

# TO STOP YOUR ACHES & PAINS

## SIMPLY USE




For more than 40 years Sloan's Liniment has been used throughout the World. It is kept ha dy in many thousands of homes to give quick, warming relief from the pains and aches of Rheumatism, Lumbago, Neuralgia, Sprains, Bruises and other severe pains. No need to rub Sloan's—it penetrates and kills the pain instantly.

*Sold by all Dealers.*

Wholesale:
FASSETT & JOHNSON, Ltd.
86, Clerkenwell Road,
London, England.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

EWO TUN L'EWO O, ẸNYIN MUNISIPA?

Ni Satide to kọja ni a gbọ pe awọn Munisipa yan diẹ ninu awọn Oṣiṣẹ wọn lati duro ni Ile Igbẹ t'ọkọnrin ati t'obinrin ni Ọnala pẹlu igbado ti o kun koroba kọkan eyiti a gbọ pe awọn oṣiṣẹ na nlo lati ma ka iye awọn enia ti o nwa gbọnsẹ nibẹ lọsan ati lalẹ ojojumọ: awọn oṣiṣẹ wọnyi si bẹrẹ iṣẹ na lati iwọn agogo mẹwa abọ di agogo mẹwa alẹ gẹgẹbi a ti gbọ: asọ pe o to ẹgbẹdogun enia ti nwọn nlọ gbọnsẹ ni Ile Igbẹ Ọba ni Ọnala lọsọsan ati lalalẹ t'ọkọnrin t'obinrin.

A koi ti mọ irufẹ ọmọ ti kika enia ni Ile Igbẹ bayi yio bi. Ka ṣi ma wo!!!

OBUKỌ DE ORUN DE.

Kosibotiri ni oworẹ ti o ti nja lati ẹnu ọsẹ mẹrin yi wa ikọ otutu ẹfọri ati aisan jẹjẹjẹ miran ni onikọ rẹ. Ki Baba ṣiju anu wo ni.

ẸJỌ IWE IROHIN DAILY NEWS.

---

Ibere Ọgbẹni Kester ọga awọn ọlọpa lọwọ Ọgbẹni Sanni Adewale.

Orukọ rẹ?

Emi njẹ Sanni Adewale.

Oniṣowo ni ọ?

Bẹni.

O jẹ ọkan ninu awọn enia Ibikunle o si jẹ ọrẹ Ọbanikoro?

Bẹni mo jẹ ọkan ninu wọn.

Iwọ ranti ọjọ Alẹ oṣu June 29 ti o kọja?

Mo ranti.

O wa ninu Mọto rẹ ni ọna Idunmagbo ni Alẹ ọjọ na?

Bẹni awa mẹrin la wa ninu Mọto.

Njẹ kini ṣe ọ ni Idunmagbo ni alẹ ọjọ na?

A ri awọn enia pe ṣuru wọn si mu iwe *Lagos Daily News* lọwọ, nwọn nwipe awọn enia ti o nditẹ lati fi Ẹtu pa Eṣugbayi Eleko ni yi—Ẹnyin ole, ẹnyin apa enia aṣiri yin tu. Awọn enia yi bẹrẹ si wo fẹtofẹto bẹni mo ni ki Awa-Mọto mi ko gbọn ere si nitoripe jẹjẹ lati nwa bọ lati ẹhin wa.

Gbogbo awọn enia na lo ha mu iwe irohin na dani bi?

Agbẹdọ, awọn to mu iwe irohin na dani tẹ silẹ niwaju wọn, nwọn nkigbe pe aṣiri nyin tu.

Ara wọn balẹ ni, tabi wọn nwo fẹtofẹto nigbati nwọn nso bayi?

Agbẹdọ, ara wọn ko balẹ. Bo jẹ pe aduro diẹ ni nwọn mura tan lati ba wa ja.

Ibere Ọgbẹni Robert lati bi ọrọ ti Ọgbẹni Adewale sọ wo,

Njọwo ni on lọ jẹjẹ ninu Mọto rẹ ni Idunmagbo?

Ni alẹ Jimọ ọjọ oṣu Juue 29.

Iwọ nlo jẹjẹ ni?

Nigbagbogbo ni Mọto mi nlọ jẹjẹ.

Nigbati Mọto rẹ ha nlọ bawọ ni iwọ ti ṣe le mọ iwe irohin kan ni *Lagos Daily News*?

Emi ri Ori iwe na ni.

Wo ibi, Iwe wo ni mo mu dani yi?

Emi ko le mọ bẹ.

Mo tun mu dani lọnọ miran, Wo!

Emi ko le mọ bẹ.

Ẹyin melo lẹwa ninu Mọto? Darukọ wọn ni kikun.

Awa mẹrin ni Emi, Saka Ẹmiabata, Bello Alufa ati Adebayọ Ijalẹ.

Iwọ ha lọ fi ẹjọ sun Ọlọpa bi ni ọjọ na?

Bo tilẹ jẹpe nwọn ndarukọ mi mọ ti Ẹtu yi emi ko lọ.

Iwọ tẹnu mọ sibẹsibẹ pe iwe *Daily News* ni wọn mu dani titi, ati pe o nwọ ..ọto rẹ lọ si ile rẹ jẹjẹ?

Bẹni.

Ẹlẹri miran ni Karimu Kọtu ti o ni on jẹ Aṣoju Oyinbo Steni & Co.

*Translated from Lagos Daily News 24/7/28.*

## ẸRI TI KARIMU KOTUN JẸ.

Karimu Kọtun ni mo njẹ, mo ngbe Ita Dosumu, emi jẹ aṣoju Oyinbo Stein Oniṣowo.

Bẹni mo wa fun Ibikunle Akitoye gbagba, mo ti ka iwe irohin ti ọjọ oṣu 29 June nipa ti tẹmbẹlẹkun ti Ẹtu-Ibọn Iwe na tẹ mi lọwọ ni dede agogo mọkanla lọ ba mejila ọsan mo nlọ kirun ni Mọsalaṣi ni Victoria Road. Mo ri awọn enia ti wọn duro ni Mọsalaṣi Jimọ nwọn bẹrẹ si kigbe mọ mi pe aṣiri nyin tu, Ọlọrun tuna aṣiri nyin, orukọ nyin yọ ninu iwe irohin iwọ jẹ ọkan ninu awọn ti wọn fẹ pa Eṣugbayi ọkan ninu awọn apa'nia. Awọn enia wọn yi fẹ sọlu mi, emi ko mọ okankan ninu wọn bẹni emi ko mọ orukọ wọn, inu bi mi pupọ. Mo rọra lọ si ile mi jẹ nigbati mo kuro ni Mọsalaṣi niwọn agogo mẹrin tabi marun ni irọlẹ mo duro ni ẹsẹ ile mi bẹni mo ri ẹniti njẹ Fọlawiyọ ti ntọka si mi.

Kiṣe ọkan ninu wa, ti awọn enia Eṣugbayi ni on ṣe, o duro niwaju mi o nsọ pe aṣiri nyin tu loni iwọ jẹ ọkan ninu awọn ti wọn nlẹ pa Eṣugbayi. Agbẹdọ ko dun mọ mi ninu, inu bi mi emi ko ja mo wọ ile mi lọ. Ni ọjọ na gan pupọ enia sọ bakanna fun mi.

Ni Satide mo lọ sode mo ri ẹnikan ti wọn npe ni Fọlawiyọ ati enikan ti wọn npe ni Badaru ni arin awọn enia miran, nwon nsọ pe iwọ jẹ ọkan ninu awọn ti wọn fẹ pa Eṣugbayi. Inu bi mi ṣugbọn mo dakẹ wọn si lọ.

Ọrọ ti Ọgbẹni Robert sọ lati bi ọrọ Karimu Kọtun wo.

Awọn enia tọka pe ọkan ninu awọn apa'nia ni yi. Nwọn tọka mi pe emi apa'nia.

Bẹni, mo ka iwe irohin nipa ti ọtẹ Ẹtu-Ibọn, orukọ mi ko si ninu iwe na, mo ri pe awọn enia fẹ ṣe laifi si mi mo lọ sọ fun Ọgbẹni Reis nibi iṣẹ awọn Ọlọpa, mo darukọ Fọlawiyọ bi ọkan ninu awọn ti o tọka mi, Reis nikan ni mo ba.

Emi ko fẹ ki Eleko pada nitori yio di ija igboro ni ilu.

*Adajọ.*—Eleko ko ni pada wa.

*Ọgbẹni Robert.*—Ẹnu ya mi fun ọrọ ti ẹnyin Adajọ sọ pe Eleko ko ni pada wa si Eko mọ. O dabi ẹnipe ẹnyin Adajọ nṣiwaju ẹlẹdẹ, nitori ẹjọ ti a nro lọwọ ki ṣe bi Eleko yio pada tabi ko ni pada bo.

*Adajọ.*—Ki yio paba bọ nisisiyi.

*Ẹlẹri.*—Fun ire ilu yi emi yio lọwọ ninu ohunkohun ti wọn ba ṣe lati ma jẹ ki Eleko pada bọ wa si ilẹ yi, emi ko mọ pe awọn enia nkọle bi Eleko ko ni pada wa si Eko mọ, Mo mọ Amusa ọmọ Ọbanikoro ki iṣe isọwọ mi temi-tirẹ ki iṣe ẹgbẹ mo mọ Ọbanikoro oloye.

Ọgbẹni Robert—Ọbanikoro ha jẹ oloye pataki ninu ti Ibikunle bi?

Karimu Kọtun—Emi ko mọ itumọ pataki ti o wi.

Ọgbẹni Robert—Ohun ti mo nwi ni oloye to ṣe kanka.

Karimu Kọtun.—Bẹni. On ni olori awọn oni fila funfun, on ni o si tẹle Ibikunle.

Adajọ—Ijọba lo fi ṣe olori awọn oloye.

Ọgbẹni Robert—Awọn oloye miran kan njẹ alafi ẹnujẹ ni.

*From Lagos Daily News, 25/7/28.*

---

## DUNIYAN—LABARI.

Lati ọwọ KEKERE AWO.

---

### ỌGAGUN RUXTON.

A ki Ọlọla Major U. F. Ruxton, C.M.G., ku abọ ọna idalẹ ti a sọ wipe o lọ, ti a si gbọ wipe o ti pada de sihin lọjọ Atalata to kọja ọjọ kẹtadinlogun oṣu—Alafia kọ ni ẹ de bi?

### ALAJI ATI AWỌN HAUSA.

Nipa ẹjọ Alaji Saka ati awọn Gambari ti a rohin ninu iwe wa ni ọsẹ to kọja pe o ṣẹlẹ latari Mọṣalaṣi-Jimọ—A gbọ wipe nwọn ti da ẹjọ na fun wọn, eyiti nwọn ni nwọn ni ki awọn Hausa bi mẹfa na san Pọnun marun-marun ni ọjọ Alaruba ọjọ kejidin-logun oṣu yi.

### ẸJỌ ONIWE-IROHIN "DAILY NEWS"

Nwọn fọn si ẹjọ yi ni Kotu St. Anna niwaju Adajọ H. A. Young K.C., lati ọjọ Jimọ ijẹsan ti nṣe ogunjọ oṣu yi.

## ILE-ẸGBẸ.

Nipa labari Ile-ẹgbẹ ti Ologbe Tom Jones ti a rohin ni ọsẹ to kọja—a ri bayi ninu labari wa na pe:—"Hall" iwe fun gbogbo enia; eyi jẹ aṣiṣe! kan, "Hall" ni o yẹ ki o jẹ fun Iranti ologbe na, aṣiṣe ni labari na.

## DAVID ỌMỌYẸLE DOSUNMU.

Pẹlu ẹdun okan li a fi gbọ ti iku Ọmọba David Ọmọyẹle Dosunmu, eyiti o ṣẹlẹ ni ile rẹ Bamgboṣe Street lọjọ Satide ijẹjọ ti o jẹ ọjọ kokanlelogun oṣu yi.

Aburo Ọba wa Eleko ni Ọmọba to ku na nṣe, o si jẹ okan ninu ọmọ-Libi Ọba Dosunmu, lẹhinna o si mbẹ ninu awọn Omọba ti o wa ni atilẹhin fun Ọmọba Eṣugbayi Eleko titi o fi tẹri gba aṣọ. A ki aya, ọmọ ati gbogbo awọn ọmọba patapata nwọn ku Ọfọ arakunrin wọn, ki Oluwa dẹlẹ fun un o—ki o si ṣọ ẹnyin iyoku pẹlu—Amin.

## IBUDO MỌTO NI BALBINA STREET.

Awọn Ọlọpa ti pa ibudo awọn Mọto Akero da ni Ita Balbina ni ọjọ Monday ọjọ kejile-logun oṣu yi,—lọ si gbangba Ajẹlẹ ni eti Itẹ-oku Igboro.

## ẸJỌ SA! ẸJỌ SA!!

Ede yi ni a gbọ wipe o mbọ lẹnu ọdọmọkunrin kan ni iwọn agogo kan oru ọjọ Atalata mọju Alaruba ni agbedemeji Adam ati Macaulay Street ni adugbo Okepopo, nigbati awọn Ọpa-ọba kan mu u ti nwọn si mbi lere wipe nibo lo ti mbọ ni iwoyi? A ko gbọ bi nwọn ti yanri rẹ si.

Ohun ti a fẹ sọ ni wipe yio jẹ anfani awọn ara adugbo na ati fun ilu gidi pẹlu, bi Ijọba ba le jẹki nwọn fa ina-oni-manamana (Electric Lights) si awọn adugbo na bi Adam Street, Macaulay Street ati Ricca Street pẹlu.

## AFARA AWỌN RELUWE NI DENTON STREET.

A gbọ wipe nwọn nfẹ yọnda ori Afara ti Reluwe ti nrin ri fun awọn enia lati ma rin lori rẹ dipo ori Afara Denton Bridge Street; yio dara pupọ bi eyi ba le jẹ bẹ, nitoripe yio mu ki awọn enia bọ kuro lọwọ Jamba ti awọn Mọto nṣe awọn enia ri lori Kereni—ati pẹlu o yẹ ki awọn Ijọba fi ti kereni Iddo si ero pẹlu, nitori pataki ni eyi na jẹ gidigidi.

## ẸNYIN—AKỌWE!

Yio dara pupọ fun nyin lati bẹrẹ si tọju iwe-irohin yi lati ọsẹ to mbọ (nipa labari Ipade ti Lọya Shyngle ni iwaju Ọlọla Gomina Clifford ni ogunjọ oṣu November ọdun 1919—nipa ṣawura ti awọn ilu ṣe ni Ẹnu Ọwa ni ọjọ kẹtadin-logun oṣu November ọdun 1919, nipasẹ dida Eleko duro) titi ao fi yanri rẹ buṣe—o jẹ ohun anfani pataki fun wa pupọ.

## MR. R. ARCHONTIDES

*Agent of the Firm of Messrs. A. J. Tangalakis & Co.*

Mr. R. Archontides Agent of Messrs. A. J. Tangalakis & Co., who took over from Mr. Jeunet early in February of this year, has created excellent record as a Tradesman of tact, and a Gentleman of amiable disposition towards Customers and buyers in general.

In spite of the slump in trade at the time he took over Mr. Archontides exhibited such commendable skill in gaining larger and steady sales and with unrelenting energy succeeded in getting back some of their old clients who have determined not buy from his firm since the departure of our Dear Friend Mr. G. A. Leventis a Greek genius in trade. These people (clients) made it their delight to obtain all their purchases from the store of Messrs. A. J. Tangalakis & Co. The African Salesman in the Store must certainly have been taken by surprise in seeing daily a crowd of buyers from the Big Traders down to little Girls enquiring for Tangala, Tangala, which means 4346, 4346. Mr. Archontides has won the admiration and affection of many customers and it may be added of his African Staff in both Produce and Merchandise lines.

Mr. Archontides has no difficulty in following the foot steps of his predecessor Ariyo Leventis. Ariyo is the name the African Staff have unanimously given to him, corresponding with the initial letter of his first name. Ariyo means a man every one rejoices to see.

Mr. R. Archontides will be leaving Abeokuta for Lagos preparatory to his going to Europe on leave. We say *Au Revoir* and not Good-bye. A happy indisposition is better than an estate of £10,000 a week. We therefore wish him *Bon Voyage* to Europe and safe return again to Abeokuta.

KEKERE EGBA.

## ADVERTISEMENT.

Irohin yi ẹniti o ba ra o ra lakai, lakai ni wọn npe ọgbọn ijinlẹ a bere lọwọ awọn igbimọ Mọṣalaṣi Jimọ pe ẹniti o kun wọn lọwọ wa lati dalẹ ni idiẹ awa diẹ oti awọn oyinbo to ngba contrak nitori wọn ko le mu brush fun ra wọn wọn juwe fun awọn contrack. Awa diẹ nigbogbo ọna asi wa ro pe James A. Cole, General Painter Contractor, 15, Richards Lane, Lagos.

Ọkunrin na wọn a ma pe ni Akerekoro ninu ọda No. 1 ẹniti o npo ọda ṣire ko si colour ti ko le po mọ. Bi iro ni wọn ba pa ẹniti o ba fẹ gbadun iṣẹ yi ko duro nibiti Lawyer Abayọmi. (1) ko bẹrẹ

ni titi nibẹ (2) ko wọ inu ẹ ko gbadun ẹ nigbangba mọṣalaṣi nibẹ ma. (3) Ko wọ ibi ashiri ti nwọn npe ni Jammiu to jẹ pe eni Jammiu to enia toto enia a ma le to joko ni bẹ ti wọn fi ngbọ wasi Lemọmu wọn nbẹ ni arin wiwo ara-bara ibẹ lo tẹni lo dubulẹ si. (4) Ibiti wọn npe ni Pulpit nibi ti Lemọmu gbe nduro si ama wọn to ọgọrun owo pupa James A. Cole yi ẹnikẹni ko ro pe yio ṣe larabara wo ẹnikẹni to ba wọ inu rẹ wọn ma ngbadun rẹ fun ni. Ti a ba si wawo iṣẹ to o ṣe si oke ẹ, oṣupa nja irawọ ntan, oṣupa nja irawọ ntan, ẹ wa wo ọla Oluwa, ẹ wa wo ola Oluwa loni Mr. James A. Cole, oṣupa ntan lọsan-gangan irawọ ntan nkan to tọ to si yẹ nipe ki Lemọmu ati awọn to to imale ki wọn pe ofiawu James A. Cole ẹhin ti wọn kọ ile na a gbọ pe on lo kun dajudaju to bẹ iṣe rẹ lati ọdun mẹrindi-logun to kun ohun ni akọkọ, ẹnkeji ohun na lo kun, ẹnikẹta rẹ on na lo kun un ara ẹkẹta yi wa jẹ olubori ka gbọ pe J. A. Cole ko gbọ pe ki wọn perfiment pe nkankan ti o ba si wa ni ṣiṣe on ni yio ma ṣe. Ẹni riri ki iṣe ẹni mimọ. Akerekoro ni a ma npe James A. Cole ninu iṣẹ ọda ko a si aripe No. 1. lojẹ ninu iṣẹ ọda, enia kọ lo fun ṣe. Ọlọrun lo gbe ade na ka lori, o kọ tan o si mọ kiroyin ti a tun ri nibẹ ni ki a gun ibikan ti wọn pe ni Soro (Tower) ẹsẹ step ti o wa nibẹ o ba ra aimoye owo. Inu Soro on ni won pe ni inu Tower. Ẹkẹrin J. A. Cole o ṣe iṣẹ alarabara ninu iṣẹ kikun o si ni Kapinta to daju ati Bricklayer to daju lọwọ, ọṣọ inu soro na di titun ẹni to ba de ibẹ a ri arabara wo niran. Ikarun, ka tun pada bọ sode ka wo oke Tower oṣupa ntan bi ọsan ati oru ka ma ṣe aniani awọn igbimọ Mọṣalaṣi lagba lọmọde ẹ ku inawo Ọlọrun ko ran yin lọwọ ko tun gbe nyin jubẹ lọ. A ki Lemọmu Jammiu pe o ku inawo A ri daju pe ki iṣe itan, a ri daju pe ẹnikẹni to ba nfẹ iṣẹ ijinlẹ ko ma wa Painter kiri mọ ko kesi James A. Cole General Painter and Contractor 15, Richard Lane. Ọga rẹ Mr. Williams W. Menco o kọ niṣe ọdun mẹjọ Apprentice ati Jonimani o kọ James A. Cole jinlẹ iṣẹ rẹ si ja gbangba arifi iṣẹ ijinlẹ ni iṣẹ tirẹ iṣẹ Furniture oyinbo funfun ko le fọwọ pa ọda rẹ loju, Lemomu Jammiu ki Ọlọrun ko ṣe iranlọwọ fun awọn to da kọbọ ati epini sibẹ ẹniti o ṣiṣẹ yi ki Ọlọrun ko ṣe ki Odumare ati awọn ọmọ rẹ a dupẹ pe Mọṣalaṣi Jimọ Eko ṣoju ẹmi. Nigbati wọn sọrọ isẹ yi, eleyi la ma fun ṣe, eleyi la ma fun mọ, wọn mọ ọ na, awọn awodi wọn nrababa. Nigbati ohun Ọlọrun wa dun. Lemọmu Jammiu ati awọn Igbimọ wa paṣẹ si, aṣẹ na wa mu ẹnitobuislailai, eyi ni James A. Cole General Painter and Contractor 15 Richards Lane Lagos. Nigbana ni awọn abiodun wa wasin. Eyi owu awi, ti Ọlọrun ni nṣẹ.

JAMES A. COLE,
*General Painter Contraotor.*

## ORI IV.

## IṢẸ.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KEJE.

Ko si ẹnikan ti o mọ riri iṣẹ ṣiṣe ju Sir Walter Scott lọ; on papa jẹ oṣiṣẹ tara. Lockhart tilẹ sọ nipa rẹ pe ti a ba wa gbogbo aiye, ti a ba wo gbogbo ilu, iru akolu iwa ti o ṣe ọwọn, iwa iṣẹ ṣiṣe lai ṣe arẹ, ki a ni ọkan ara ẹni, ki a si mọ hu bi ti Scott, ti a ba nwa nibo ni a le ri iru iwa yi, larin awọn ọba rere tabi awọn balogun rere ni a le ri i ju larin awọn ọmọwe lọ. Scott papa du lati mu ki awọn ọmọ rẹ mọ riri iṣẹ ṣiṣe pe eyi jẹ ọna ti enia fi ijẹ nkan ti isi fi gbadun laiye. O kọwe si ọmọ rẹ Charles nigbati o wa ni ile iwe, o ni: "Emi ko le ṣẹṣẹ ma tẹnu mọ fun ọ pe iṣẹ ṣiṣe (lala) jẹ dandan ti Ọlọrun fi le fun wa ninu ipo-kipo ti a ba wa; ko si ohun kan ti enia le ni, ti ko ba ṣe ki o to ni i, ti o jẹ ohun ti o yẹ ki a ni; bẹrẹ lati ibi onjẹ ti a njẹ, ti agbẹ a lagun ki o to mu jade, titi de ere ọdẹ ṣiṣe eyiti ọlọrọ ma nṣe lati gbanra nu, . . . Ni ti ẹkọ tabi imọ eyi ko ṣe gbin sinu enia lai jẹ pe a ṣe lala, bi a ko tilẹ ni oko igbado tabi erẽ lai jẹ pe a ti ro ilẹ ṣiwaju. Ṣugbọn iyatọ nla kan yi ni o wa, nkan le ṣẹlẹ tabi ohun kan le ṣe ti o le mu ki ẹlomiran ko ere ohun ti agbẹ gbin; ṣugbọn ko si eṣi tabi ofo kan ti o le mu ki ẹnikan gba ere ẹkọ ti ẹlomiran kọ lọwọ rẹ; ẹkọ ti o ye goro ti a si kọ jẹ ti ẹni ti o kọ ọ. Nitorina, ọmọ mi ọwọn, ma fi akoko tafa, tẹpa mọ iṣẹ. Ni igba ewe ara wa fẹrẹ, ori wa si ya, ẹkọ ko si ṣoro lati kọ; ṣugbọn ti a ko ba fi owurọ wa ṣiṣẹ ẹtẹ ni a o ri ni ọsan wa, iyangbo ni ere oko ti a o ko, atubọtan wa ko ni ni iyi, alẹ wa ko si ni ni adun."

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

## ẸNI PE AGUNTAN LAGBỌNRIN A RU ORIRẸ DE JỌBA!

Iwa ti awọn awa motor nhu ni ọna oko jẹ iwa eyi to lewu lọpọlọpọ. Ni ọjọ Sunday to kọja

tokọja yi ni awọn enia meji kan ngun kẹkẹ Ologere lọ ni ọna Agege ti awa mọto Reo kan L155 ba awọn ọgbẹni wọn yi lọna, o fẹrẹ ṣe wọn leṣe, tobẹ ti enia meji wọnyi fi gbe basikulu wọn wọ gbẹ lapapa dodo ki awa mọto yi to ya lẹhin wọn a ko mọ ohun to kọlu awa wọto na baya ori rẹ loyi a bẹ awọn Ọpa Ọba ki wọn ba ni ṣe akiyesi Ọgbẹni awa mọto na ni akoko yi lọna ibi ki bi boya Agege ni kan lo nlọ a ko mọ o.

OṢELU.

---

## IROHIN ILE-IFẸ

Irohin kan Ọgbẹni E. T. Adewọnyin Coker, ẹniti o jẹ ọmọ aburo Ọba Ọni ile-Ifẹ ti o wa ni ile alarun Dokita Gray fun itọju wipe ọkan ninu iyawo ti o fi silẹ ni ile-Ifẹ ti ko mu wa si Eko bi ọmọkunrin kan fun Ọgbẹni Coker ni ọjọ *Sunday* ijọ kejilelogun oṣu July 1928. Aburo rẹ Prince Adeyẹmi lo tẹ waya irohin ayọ ọmọ bibi yi ti Ọlọrun fi ta ile Ọba lọrẹ. Ọgbẹni Coker a ba ọ yọ, Ọlọrun ko mu ẹ de ile-Ifẹ ni alafia ko le fi oju rẹ kan ọmọ rẹ na.

---

Irohin kan ni wipe ọdọmokunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Belo o ti nṣiṣẹ Ekurọ ni Ẹdẹ Siteṣanni fun awọn oyinbo oniṣowo, jalaisi ni ile-Itẹ. Ọdọ mọkunrin yi jẹ aburo aya ọmọ Ọba Adeyẹmi ti orukọ rẹ njẹ Jeje. Ki Ọlọrun ko fi si atẹfẹ rere. A si ki Prince Adeyẹmi pe o ku ọfọ ana rẹ.

---

## IROHIN LATI ENUGU.

---

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*, Lagos.

Inu mi dun lati ri wipe awọn Yoruba ti o wa ni ilẹ yi lati ọdun 1925 ṣẹṣẹ wa ni Ọba pataki ti o si jẹ olotọ larin wọn. Ẹniti orukọ rẹ a ma jẹ Mr. & Chief Samuel Animashaun, ẹniti o jẹ ọmọ bibi Eko ni No. 6 Luther Street, Lagos. Awọn agbagba ti a o ka wọnyi: ni awọn ẹniti o jẹ pataki ti o yan ni Ọba: ni ọjọ *Thursday*, 3/5/28.

1. Mr. Aminu Megida,
2. ,, Alufa Sadiku,
3. " Yesufu Eko,
4. ,, James Alabi,
5. ,, Alọmasonle,
6. Madam. Lanlatu Adekunle, Iya-Ẹgbẹ.

Ọjọ na dun tobẹ ti Arọ fẹrẹ ni ki wọn gbe on wa wo iran ni opopo. Ilu gangan ati kakaki Hausa ndun, ti gbogbo rẹ ndun yungba, Ọba yi si nawo pupọ ni ojọ na: Abusi Oluwa ati ọpọlọpọ alubarika si iṣẹ Ọba na, amin.

Iṣẹ ti Ọba Yoruba na nṣe ni iṣẹ gbẹna-gbẹna ati Contractor ni igboro ilu Ẹnugu. A o rohin Iwuye rẹ ni ọjọ miran.

Emi ni ti nyin nitotọ,
KOREDE.

---

## Mr. T. Adenrele Kester.

Congratulation to Mr. T. Adenrele Kester son of Mr. & Mrs. T. I. Kester of this town on his success in his first year's medical Examination in the University of Edinburgh, when he passed in Botany, Zoology, with distinction in ANATOMY.

---


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

Eko, Saturday, July 28, 1928.

## OWO ORI, OWO OLOGBO ASAN 'SANTAN.

Lati ibẹrẹ oṣu yi ni a gbọ pe awọn enia ti nwọn ko si ninu Iṣẹ-Oba ti nlọ sanwo Ori eyiti a ti fi iwe rẹ ṣọwọ si nwọn lati Ibi-iṣẹ Aṣoju tabi Alaṣẹ Ilu ni Mọgaji eti wa si kun pupọ fun imi ẹdun ati aroye ti a sọpe pupọ ninu awọn enia ti nwọn nlọ lati sọ ti ẹnu wọn na nṣe nigbati nwọn de ibẹ.

A gbọ pe ẹnikan ti a ti fi iwe sisanwo na ṣọwọ si lọ si ibi-iṣẹ yi pẹlu aṣọ ti ko jẹ aja jẹ ti ko si jẹ ẹra buṣan, lati bẹ ẹbẹ pe ki Ijọba fi oju anu wo on nitoripe on ko ni iṣẹ lọwọ on kosi ni abọ lẹsẹ lati bi oṣu pupọ sẹhin; de ipo pe ki on ri owo lati san owo ori.

Wahala nlanla ni sisan owo ori yi yio ma muwa nitoripe ki ṣe owo ti ẹnikan le san lọdunni ki o ma si san lọdun miran ayaṣebi oluwarẹ na ba lọ si idalẹ tabi ki o jalaisi!! idiẹ niyẹn ti a fi pe owo asingba sisan yi ni owo Ologbo asan-isantan.

Titi di isisiyi a kọ ri ki Gomina Agba kede rẹ sinu Iwe Irohin ọsẹsẹ Ijọba pe irufẹ awọn Akuṣẹ bavi bayi tabi awọn ẹlomiran ki yio ni ọwọ ninu owo-asingba yi ni sisan gẹgẹbi o ti ṣe ni ọdun tokọja nigbati Ajọ Igbimọ Aṣofin Ijọba ṣi nṣọpalaye ṣile mẹwa mẹwa ni sisan lati ọwọ olukuluku ọkọnrin ti o ba ti di ọmọ ọdun mẹrindilogun tabi jubẹlọ; ọkan ninu inira ọpọlọpọ ti sisan owo ori yio muwa tabi ti o ti muwa nipe awọn onile yio bu owo si hihaya ile wọn boya ile ti ko ti ju £1 oṣu ri ni hihaya le di £1 10 nigbati onile na ba ṣiro owo-ori ti Ijọba fẹ pe ki on sa san lori ohun ini on: irufẹ inira ti o mbẹ ni Ilu Oyinbo nibiti ilaju sisan irufẹ owo yi gbewa ni o mbọ wa si Eko diẹdiẹ yi; Kini Ijọba tilẹ ti ro ti gbogbo Mẹkunnu Eko si ati ọgọrọrọ awọn ẹni ti ko ri ṣẹṣe lati ọjọ jọjọwa? Nitotọ sisan owo yi ko jẹ ohun ti o ni awọn ẹlomiran lara nitori nwọn ni iṣẹ ti o to iṣẹ lọwọ, ṣugbọn ika ha le dọgba bi? A ṣebi olukuluku enia lo mọ ibiti bata on nta on lẹsẹ ẹniti o ṣi ṣabu rẹ silẹ ti ko si pa tọrọ (3d) pa sisi (6d) lojumọ titi ilẹ ma fi ṣu, ti o si ni ẹru lakata ile rẹ lati rù kọ ni o ma sọpe ara dẹ on ki a ma tilẹ ti so ti inawo pẹpẹpẹ miran ti o ni lati ma ṣe lojojumọ bi o fẹ bi o kọ.

Ṣasa nkan loku ti Ijọba ki gba owo rẹ lọwọ ara ilu Nigeria pẹlu awọn Ajeji miran; Ijọba ngbowo omi, Ijọba ngbowo ẹdu gige ninu Igbo, Ijọba ngbowo ina, Ijọba ngbowo ọna titunṣe, Ijọba ngbowo Moto, Ijọba gbagba titi nwọn ngbowo Ori; kilotun ku, Ijọba fẹrẹ le sọpe awọn yio ma gbowo afẹfẹ ti a nmi: ni gasikia anfani nkan wọn si fi ara han li ọna titunṣe fun Mọto ki o ma sare gere, ṣugbọn inira fẹrẹ pọ pupọ ju gbogbo awọn anfani yi lọ: owo Yanmuyamu ti awọn Munisipa ti ngba ko ha to tẹ odidi ilu kan do lati ọdun mọdun ti nwọn ti ngba yi wa, ta lo le sọpe asiko awọn baba baba wa ko san ju igba yi lọ, njẹ ọpọlọpọ enia kọ lo nsọpe ẹniti o ku lo bọ lọwọ muwa muwa gbogbo wọnyi.

Nigasikia Ijọba pa ọwọ ẹru rẹ ṣugbọn ipo ẹru ti owo ori sisan yi fi Nigeria si ko ha buru ju ẹru tita igba lailai bi? Talo le sọpe ọlọgbọn ẹwẹ ti o ju awọn Gẹsi lọ wa? Lati akoko Gomina Moloney ni ọdun 1889 ni Ijọba ma ti nfara gbigba owo ori yi ni Eko bọ ti awọn ara igbani fi nkọrin bayi pe!!

"Moloney ṣẹ'gi ẹra
Iwọ, Iwọ, ni o para rẹ"

Ẹ jẹ ki a tilẹ ka awọn orukọ Gomina ti o ti njọba silẹ yi lati ọdun na:—

| | | |
|---|---|---|
| 1. | Gomina | Moloney |
| 2. | ,, | Cater |
| 3. | ,, | Denton |
| 4. | ,, | Macgregor |
| 5. | ,, | Egerton |
| 6. | ,, | Lugard |
| 7. | ,, | Clifford |
| 8. | ,, | Thomson. |

Nigbati o si di ọdun kọkanlelọgbọn nkọ, lẹhin rẹ owo na ko ha di gbigba bi lọwọ ara Eko ati gbogbo ilu to mbẹ ni Nigeria loni ni akoko Gomina Thomson ?

Lọwọ gbogbo Inira, airişẹşe, gbigba lọwọ meri, wahala Ebi, Airi ilegbe, Aisan ati inira oniruru gbogbo. Oluwa rere gba wa.

---

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Jọwọ gba mi ni aye diẹ lati sọ ọrọ diẹ ninu iwe rẹ yi nitori Ọgbẹni Emanuel Timothy Adewọyin Coker, ẹniti o wa ni ile alarun Dr. Gray ni Alli Street ni Eko, ẹniti Olotu iwe irohin *Daily Telegraph* sọ labari diẹ ninu iwe irohin rẹ ni ọjọ *Friday* ogunjọ oşu yi. Ọgbẹni Coker yi jẹ ẹniti mo mọ daradara ẹniti iya rẹ ologbe Ọlọrun ko fi ọrun kẹ loni, ki Ọlọrun dari aşişe rẹ jin, jẹ aburo Ọba Ọni Ile-Ifẹ loni yi ni ọmọ inu iya kanna. On ni ẹniti o bi Coker ti mo nsọ ọrọ rẹ loni yi Ọgbẹni Coker yi jẹ ẹgbọn Prince Adeyẹmi ẹmọ Ọba Ile-Ifẹ, Ọba ti o wa ni ori oye Ọba loni yi *Kabiyesi Alaşẹ Ekeji Orişa.* Ọgbẹni Coker jẹ olotu ibişẹ awọn oyinbo W. B. Mac Iver & Co., ti Ile-Ifẹ lati ọdun 1922 lo ti nba işẹ rẹ bọ, lai si ikọsẹ kan tabi wipe ọja tabi owo din si ni ọrun titi o fi di oşu May 1928, ko to fi işẹ na silẹ nigbati ailera de si *Ọluwa ki o gba ni ninu amudi ara, amin.* Nigbati Ọgbẹni Coker wo oye wipe aisan nşe on lara lati bi ọsẹ meji yi wa, o wa ronu o bere lọwọ Ọlọrun rẹ gẹgẹ bi a ti le wi wipe ko si şişe ju wipe ki on mura ki on ma bọ ni Eko. Ọpọlọpọ enia lo mọ ile Ifẹ ọpọlọpọ si ngburo ile Ifẹ wipe ile waşẹ ni, şugbọn ki ẹnikan wa dide larin gbogbo okiki yi pẹlupẹlu ẹniti o tun jẹ aburo Ọba ko gbaradi ko ni onişegun oyinbo li on ma tọ lọ ẹnyin ara wa ẹ ma ri işẹ ilaju lode aiye loni.

Ọgbẹni Coker gbe Mọto rẹ *Morris Ox-ford* si oju ọna pẹlu amudi ara rẹ o mbọ ni Eko, irin bi adọsan mile ni Ifẹ si Eko nibi, *Larin iye awa mbẹ ninu iku* Ọgbẹni Coker de si Eko ni ijọ kẹtala oşu June 1928, Dr. Gray gba sile alarun ni ijọ kejidilogun oşu June 1928, Dr. Aitkens la ni ijọ kọkandinlogun oşu June 1928 :

> *( cperated upon by Dr. Ailkens on the 19th day of June 1928, the iudentical date that cable announcing the approval of ihe Eleko's Appeal in the Privy Council was announced )*

Ọjọ ti Dr, Aitkens ti ọbẹ bọ ni ara ọjọ na ni w a y a d e l a t i ilu oyinbo wipe ẹjọ Ọba wa Eşugbayi Eleko awọn adajọ mẹta ti Kotu nla *Privy Council* gba ẹjọ wipe nwọn ni lati tun gbọ nilẹ yi lori ohun ti o pati mimu lọ rẹ. Ẹnyin enia wa ẹni nla, nla lo ma ma jẹ. *Ewi kekere ko ni ru nla* ẹ wọ ẹniti a nsọ ọrọ rẹ ọgbẹni Coker yi, o jẹ aburo Ọba tabi ẹniti a le pe ni ọmọ Ọba gẹgẹ bi ipo ologbe iya rẹ ẹniti o jẹ aburo Ọba Ọni ile to wa ni ori oye loni yi, ijọ to gbe ẹmi rẹ le Ọlọrun lọwọ ọjọ na ni irohin ti de fun Ọba wa Eşugbayi Eleko wipe ẹjọ rẹ ko ni tan bayi wa tun tun gbọ, gẹgẹbi Coker ti yege ninu ewu rẹ Ọlọrun ko jẹ ki o yege ẹjọ rẹ yi amin. Ọgbẹn Coker yege, şugbọn o şi wa ni ile alarun ki oju ẹgbẹ rẹ le jina. Ni were ti irohin de ile Ifẹ wipe o yege waya ati iwe npe arawọn ran-nişẹ lati bi ọdọ Ọgbẹni M. D. Akinyẹmi, A. Aderẹmi, E. O. Shanu, ati awọn jakan-jakan lati ile-Ifẹ, lẹhin ọjọ mẹtalelogun ni ọmọ Ọba Adeyẹmi ati aburo rẹ obinrin Marian Adelaju aya Ọgbẹni Kasunmu ọmọ Chief Lowa ẹniti baba rẹ je ọkan ninu awọn adajọ pataki kotu ile-Ifẹ wa ki Ọgbẹni Coker gẹgẹ bi ipo tabi aşoju ile Ọba *Representatives of the Royal House.* Emi ko le şe alai gbe ẹnu le enia ti Ọgbẹn Coker jẹ, o kọ ile nla pẹtẹsi si Main Road ni Irẹmọ Street ni ile-Ifẹ ile to jẹ wipe o ngba alejo k' alejo to ba wa si ile-Ifẹ wa mọ ilu si yala o mọ oluwarẹ ri ni tabi ko mọ yio şe oluwarẹ ni alejo jijẹ ni mimu ni ba kanna.

Ọgbẹni Coker si wa ni ile alarun nisisiyi boya titi ipari oşu yi Dokita yio da silẹ yio wa mu ọna pọn pada lọ si ile-Ifẹ, igbakigba to ba wu ki Dokita da silẹ, ki Ọlọrun ki o pa alọ rẹ mọ ati aya rẹ to mu wa, ki wọn si ba ile ni alafia ki Oluwa si jẹ ki o ba Uncle rẹ Ọba Ọni ile-Ifẹ ni alafia " Kabiyesi Alaşẹ Ekeji Orişa, " ki Ọba ko pẹ.

Emi ni tirẹ nitotọ,

ENIA KODI ALLAH

---

## NWỌN NGE NYIN LỌWỌ, Ẹ NBỌ ORUKA.

APA KARUN.

---

Ni ọdun 1924 ti Arun yi ti bẹrẹsi ja di ọdun yi, ọpọlọpọ ẹlomiran lo mbẹ loni, ti aya, ọkọ, ọmọ, ẹbi ibatan, ọrẹ, arota, baba ati iya ku iku aisan-ode yi ti awọn *Municipal* şi ki mọlẹ ti nwọn gbe digbadigba lọ si ile laku-laku, lẹhin ti nwọn yẹ oku na wo tan, nwọn ri wipe Ajakalẹ-arun lo pa oluwarẹ nwọn lọ sin i fun arawọn, awọn ara oku yi ko mọ ibiti Şare gbe wa bi dudu bi funfun ni debi ti nwọn ma lọ fi ọwọ dan orori na wo, eyi to ẹkọ fun wa ti a ni lati ma sun ki a ma ronu daradara ki a ma fi kọ ẹgbọn pẹlu, awa si mọ wipe ẹniti o ba lọ kan lọ mọ, ẹniti ko ba kosi eyiti o kan ninu gbogbo iregbe ti a nwi yi, ẹniti atẹgun ọrọ

ti a nsọ yi tilẹ fẹ bu u, o sọ wipe on ka ohunkohun si nkan.

Wayi o, lode ti a wa ninu rẹ yi oriṣiriṣi iku lo mbẹ, ọnakọna ni enia ngba ku ni ilu yi ni aseko yi, ọpọlọpọ lo nti ipa ọna agbere ṣiṣe yọ si Kiyaomọ lagbara, bẹni ọpọlọpọ lo si npọka-iku bi a ti nsọ lẹnu yi, ti o jẹ wipe bi a ba wa kakiri, iwa agbere lo fa aisan wọn a kole sọ ti ogunlọgọ ọmọ Anabi Adamọ ti o ti rekọja si Kiyaomọ nipa agbere ṣiṣe, pẹlu bayi na ni ẹlomiran tun nku iku aburadi lai ṣe aisan ọjọ gbọrọ, iku ojiji lo tilẹ pọju ni ilẹ yi loni—ki olukuluku lọ tọju iwa rẹ, nwọn ni bi Ọlọrun ba nṣọ ni, o yẹ wipe ki awa na ma ṣọra'wa.

Awọn ẹlomiran tilẹ gbe ogun iṣẹ asaba yi ka'ri tobẹ ti ẹlomiran fi nṣe egbogi arun-karun maṣe le ran wọn, tabi bi iru egbogi ti nwọn fi le ma fi ba ọkunrin sọrọ lai le yi ẹnu pada lati gba ohun ti nwọn nwa lagbara (ṣaṣa ọkunrin lo ma ti jagbọn wọn kẹ o) nwọn a ma wa rafanda loju, lẹhin ti nwọn ba ti ri oluwarẹ bo mọlẹ—kosi itu ti o ku ti nwọn ki ipa tan lọna bayi, eyiti ko tọ fun wa lati ṣe, ṣugbọn ti awọn onibanbaṣi ọkunrin ẹgbẹ wọn ti mọ bi ẹni mọ owo.

Ọkunrin miran a wa, yio ma gba bi Pọnun mẹrin tabi marun ni ibi iṣẹ rẹ loṣoṣu, ti o si jẹ wipe bi a ba ni ki a ṣiro iye bukata ti oluwarẹ le ma ṣe ni larin oṣu kan yio fẹrẹ to ilọpo meji iye ti o ngba nibi iṣẹ, pẹlu bi bayi nkọ, bi oluwarẹ ṣeṣi ko firi awọn olori buruku na, ko kọ lati na Owo oṣu kan ti o ngba le lori, ki oṣu to pari yio ti jigbese silẹ rẹpẹtẹ, eyiti owo oṣu mẹta kole ka bi nwọn o ti ma tọ ipasẹ ọna yi lọ nu ti aṣọ egbere ko ni fi ka egbere ti fila wọn ko fi ni wọ janma; ọmọ aya awọn obi ma mbẹ ni ile ti irufẹ awọn ẹni bẹ le ma gbọ bukata fun, bawo ni obinrin ti ile ko fi ni bẹ si ilu lati ma ṣe iṣẹ ti ọkọ rẹ papa nṣe? Awọn obi papa yio ma kigbe wipe lagbaja nibo lo gbe nko owo iṣẹ ti o nṣe si, kilo fi nṣe, nwọn tilẹ mọ iye ti o ngba na, debi ki nwọn sọ awọn yio fi oju ganni rẹ.

Sibẹsibẹ lori gbogbo ọrọ yi lori awọn obinrin ni o ṣi ṣẹ'pa si loju wa, nitori o da ni loju pe bi olukuluku obinrin ba kapa ọkanjua rẹ ti nwọn ba si ni ero lori daradara dajudaju aye iwa agbere kole gbilẹ lọkan wọn tobẹ—ani bi awọn obi tikalarawọn ki iba nṣe onijẹkujẹ ti nwon fi le yangan lati kapa lori ọmọ wọn ani bi awọn ọmọge ba sun pẹtẹ ti nwọn ba nronu arawọn wo daradara, ti nwọn ba nfẹ ki ara ro wọn ninu igbesi aiye yi, ani ti nwọn nba nfe ki nwọn gbo ki nwọn tọ, nwọn ni lati kuro ni idi iwa panṣaga gẹgẹbi a ti nsọ wipe ọpọlọpọ obinrin lo ti bajẹ ti nwọn si ti balumọ pẹlu, awọn ti o ni ero lori ti nwọn si ri wipe iṣẹ aitọ ni iṣẹ agbere ko to nkan laseko ti a wa yi, a ko sọ ti awọn ara igba ni ti nwọn tọju ara wọn gidigidi ti nwọn si nni ọjọ lori ki nwọn to ku.

Awọn obinrin sa lailai, omiran nto adọta tabi ọgọfa ọdun ki o to ku, eyiti ọjọ rẹ kere patapata gba ni ọgọrun—ngbọ loni nkọ kò ha di ṣaṣa lati le ri irufẹ awọn ẹni ti ọjọ wọn le gun bayi ki o to ku ! kosi ohun meji ti o mbẹ nidi rẹ, nigbati nwọn ba ti fi igba ewe wọn lo ara danu lọna aitọ bayi, eyi kole mu eyi ṣẹ arara—eyiti a ba ri ti o ba to adọrin laseko yi ọga patapata, a jẹ wipe lara awọn ẹniti o ntọju ara wọn ni igba ọmọde wọn ni, a si ni lati yin iru awọn ẹni bẹ gidigidi, kosi ohun meji ti o mu ikẹhin aiye dinku, bikoṣe iwa aitọ.

*(Koi pari)*

ỌMỌ—ILU.

## Olusakin's Column.

PLEASANT HOURS WITH PRINCE ADEYEMI OF IFE

*(By a Correspondent)*

**The rank is but the Guinea's Stamp.**
**The man's the gowd for a That"—Burns.**

For unaffected simplicity and real worth and that human sympathy which wins the affection and regard of others one is strongly reminded of that bonnie Prince, the great Ambassador of the Empire H.R.H. the Prince of Wales by that popular son and heir of the Oni of Ifẹ, Prince Adeyẹmi, who with his Sister, came down to Lagos on business last week and was lionized by all who came into contact with him.

Among the many entertainments in his honour the luncheon by Mr. Oke Adeshigbin, Manager of the Singer Sewing Machine Agency, at Bamidupe House, Apapa Road on Sunday last, and the Dinner by Mr. J. Ọmọṣalewa Thomas, (popularly known among his circle of friends as Prince of Ọnọṣokun) at Oyigbo Market on Monday, showed best the high regard in which he is held.

Mr. Oke Adeshigbin who, true to his family traditions, is unassuming, modest and highly patriotic, made his guests "at home," and the Prince, without any introduction or eulogium from his host, revealed his true character to all before he was many minutes in the midst of his new acquaintances, and it was with general regret that the Company broke up after some four hours of a most pleasant time.

The happiest result of the luncheon party was the tussle for the honour of playing the host to the genial Prince on the morrow which was won by Mr. Ọmọṣalewa Thomas with right honourable amends on the evening of the 9th when his chief competitor was made completely happy by the way in which the self-imposed task was discharged from 8 to 11.30 p.m.

There were at the board besides the Prince Adeyẹmi and Princess Adelaju, Barrister Ekundayọ Williams, who presided at the table, Prince Okunade of Ilesha, Barrister Andrew Ọlatunji Thomas, brother of the host, Mr. A. J. Marinho, Jnr. Mr. D. A. Bright, Mr. E. A. Oluyẹle Bright, Mr. I. O. Ogunlanọ Mr. A. B. Williams, Mr. A. B. Laotan, Mr. Oke Adeshigbin and others. With the sumptuous dinner went free drinks, but no less enjoyed were the toasts. The speakers were :—

Toast of the Alaiye-luwa, the Ọni of Ifẹ— Prince Okunade

Response—Barrister A. O. Thomas

The Owa of Ilesha—Prince Adeyemi

Response ... Mr. D. A. Bright

Prince Adeyẹmi and the Princess Adelaju Mr. Oke Adeshigbin

Response (*Chairman*) T. Ekundayo Williams

The Host ... Mr. A. J. Marinho Jnr.

Response ... „ J. Omoshalewa Thomas

The Race ... „ A. B. Laotan

Response ... „ E. A. Oluyele Bright

The Stewards „ I. O. Ogunlanọ

Response ... „ Alfred B. Williams

The strongest note from the various speeches—and they were all in various styles and of varied interests—was the promotion of national cohesion by inter-tribal friendship and co-operation.

The Prince whose hospitality and friendliness in his royal domain were so warmly praised by Mr. Adeshigbin has no doubt carried away no doubt carried happy memories of their last visit to Lagos.—*The Nigerian Spectator*, 14/7/28.

———

### Bishop Howells.

It is stated on good authority that the Right Rev. Bishop A. W. Howells, M.A., D.D., Assistant Bishop of the Niger sailed by the *R.M.M.L. Adda* from Liverpool on Wednesday, the 18th July, 1928, and is expected to arrive Lagos on Thursday next the 2nd proximo.

To Mrs. Howells we say ẹ ku afoju sọna.

———

### Sir Ofori Atta.

Nana, Sir Ofori Atta, Paramount Chief of Akim Abuakwa, Gold Coast, was among the passagers who sailed from Liverpool on the 18th instant, by the *R.M.M.L. Adda* for the Gold Coast.

### Wedding Bells.

A marriage took place at Christ Church Pro-Cathedral on Tuesday, the 24th July, 1928, at 3 p.m., between Mrs Georgiana Adebisi Marsh (nee Martins) daughter of Mr. F. Germano Martins (Pensioner) of Alli Street, Lagos, and Mr. Julius Claudius Johnston (Widower), Chief Native Surveyor, of "Bee Hive" 4, Taiwo Street.

Rev. M. S. Cole, M.A., Vicar of the Christ Church Pro-Cathedral officiated.

We wish the Bride and Bridegroom for their second time in marriage a long life, happy home, and all connubial bliss.

Oluṣakin.

———

### ẸRI ỌGBẸNI HERBERT MACAULAY, C.E.,

Ni ijẹrin ni Ọgbẹni Herbert Macaulay jẹri tirẹ o sọrọ lọ bi ilẹ bi ẹni pataki ohun ti on ni ṣoki leyi :

(1) O mu on lọkan pe agbọsọ ti ọtẹ Etu Ibọn na f' ẹsẹ mulẹ ni ilu lẹhin igbati on ti ro opọlọpọ ohun ti on jẹ gbigba yẹwo.

(2) Pe on mọ dajudaju pe Prince Eṣugbayi Eleko yio de silẹ yi, kete ti Kotu ba ti f' ọwọ si aṣẹ Habiasi Kọpọsi.

(3) Pe ki iṣe awọn euia ti on wi o nda rugudu silẹ ni ilu.

Idajọ di ọtunla. A o sọ iyoku ni kikun l'ọsẹ to mbọ, lagbara Baba.

## OBITUARY.

———

The death is announced of Prince Ibikunle Akitoye as have taken place at his residence Upper King Street, and his corpse was removed at 2.30 a.m. to Iga Idunganran to belaid instate.

———

### IKU MBẸ!!!

Gbukẹ ni a gbọ pe Prince Ibikunle Akitoye jalaisi ni ile rẹ ni Upper King Street ni oru Friday, nwọn si gbe oku rẹ lọ si Iga Idunganran tẹtẹ ni agogo meji abọ oru ki ilẹ to mọ

## Advertisement.

Vacancies occur at Ijora and other Stations in Nigeria for a number of experienced boiler house engine from attendants.

Applications will only be considered from men having previous experience with high pressure boilers and high speed reciprocating steam engines.

Commencing Salary from £72 to £88 per annum, according to qualifications. Full particulars of experience and training should accompany applications, which should be in writing and addressed to the Director of Public Works, Lagos.

## Attention ! Attention ! ! Attention ! ! !

FOR BUYERS IN GENERAL.

HAVE YOU BEEN AT

### IWA=JO=WA STORE, ( No. 1 & No. 2 )

IF NOT, WHY NOT ? AN OPPORTUNITY ONCE LOST CAN NEVER BE REGAINED.

The undersigned have in Stock for sale at unbeatable—prices not obtainable else-where The following cheapest materials are kept in Stock.

**Rubby, Rubby, Rubby !**

*( Again and again, "Gbangba dẹkun" Kedere bẹ wo. )*

**Goldsmith Tools :—**

Pickers, of any kind or size
Plowpipes, of any kind or size
Scissorses, do.
Drawplates, do.
Brass mouldings, do.
Hand Scale, do.
Brass Lamps, do.
Screw Plates, do.
Cutting and doming punches of any kind or size.
Assorted kinds of Files,
Bellows of any description

Bench Vices, of any description
Crusibles, do.
Kegs of saltpetre,
" " Alum,
" " Borax
Pure Silver grains, too numerous to mention.
Capentory Tools of any description
Shoemakers, do.
Sawyers, do.
Bricklayers tools of any description
Bicycle accessories do. etc. etc.
Seeing is believing ;

*" Ganni ya fi ji."* Irohin ko to afojuba.

Apply to Proprietors D. ODUSANYA & BROS.,
*Expert Goldsmiths.*

45, Princes Street. Isalẹgangan, Lagos,
20, VictoriaStreet, Lagos.

*Cable Address :—*
**Iwajowa Store No. 1,**
45, Princes Street, Lagos.

## We are sole local Agents for

# Vibrona

*The Ideal Tonic Wine.*

---

SURPASSES ALL OTHER WINES

AS A

## TONIC STIMULANT

AND

## INVIGORANT.

**VIBRONA** has been justly described as the **Supreme Tonic,** and the world-wide reputation which it enjoys is mainly due to the personal testimony of those who, having experienced its remarkable energising powers, are glad to recommend it to their friends.

A liqueur-glass of VIBRONA, taken either alone or with a plain biscuit, is almost magical in its effect as a Tonic Restorative.

---

**The modern Discovery for Female sufferers is**

## Wireless Female Pills

**A sure remedy against all kinds of monthly disorders experienced by women, and an effective vitaliser against harreness. 4/6 per bottle of 72 Pills.**

## Kaduna Balm 1/-

**The family Remedy applicable in 100 different ways. Indispensable during this rainy season.**

## Saccharine 1/-, 1/6

## Anti-Rhumatic Salt 2/- and 3/6

## Rheumatism Pills 1/6

## Yaro (*small and large*) 2/3 & 3/3

## Pile Pills 1/6

## Pile Remedy 7/6

## Cooling Blood Purifier 7/6d.

**(A powerful blood cleansing Preparation).**

## Gonorhea Remedy 7/6 & 4/6.

**Works with effective rapidity.**

***Dr. De Roos' concentrated Guittae Vitae for general Debility, shaking of the hands and limbs, dimness of sight &c., miraculous curer, largest size £2. 2. 0.***

Special Wholesale Price.

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
*Branches*:—6, Martin's Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109 Griffith Street, Ebute-Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.

41, Offin Road, Lagos.

*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati orişirişi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

**PRICE 10/- PER BOTTLE.**

**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.

41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist*,

The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba rọ to. Aşẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

## One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

———:o:———

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmi
ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orișirisi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju
si Ile Niger ni No, 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorișirisi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba,
awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun
ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 2D, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.